Ẹnikẹni ti ó bá ṣamojuto ọmọ obinrin meji tabi tí ó tọ́ wọn dagba titi ti wọ́n fi di ẹni ọkunrin, irufẹ ẹni bẹẹ yóò wá ní ọjọ igbende ti èmi rẹ yóò wà papọ̀" Anọbi pa ọmọnika rẹ papọ̀ mọ́nrawọn

Lati ọdọ Anas ọmọ Maalik, ki Ọlọhun bá wa yọnu si i, o sọ bayi pe: Òjíṣẹ Ọlọhun - Ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa ba - sọ bayi pe: "Ẹnikẹni ti ó bá ṣamojuto ọmọ obinrin meji tabi tí ó tọ́ wọn dagba titi ti wọ́n fi di ẹni ọkunrin, irufẹ ẹni bẹẹ yóò wá ní ọjọ igbende ti èmi rẹ yóò wà papọ̀" Anọbi pa ọmọnika rẹ papọ̀ mọ́nrawọn.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi - ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa bá a - jẹ kí amọn pé: ẹnikẹni ti Ọlọhun bá fun ni ọmọbirin meji tabi arabinrin meji, ti o wa mojuto itọju wọn daada pẹlu ẹkọ ati titọwọn sọna lọ sibi iṣẹ rere, ti o sì ṣọwọn lára kuro nibi aburu ati bẹẹ bẹẹ lọ titi ti wọ́n fi dagba, irufẹ ẹnibẹẹ yóò wà pẹlu Anọbi - ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a - ní ọjọ igbende gẹgẹ bi ika ọwọ méjèjì yii, Anọbi ṣe àpèjúwe rẹ pẹlu ika ilabẹ ati ika mogajuwọnlọ tí ó pa wọ́n pọ̀ mọ́nrawọn.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3360